Wikipedia
Ìwé Ìmọ̀ Ọ̀fẹ́

# Ìpínlẹ̀ Èkó

**Ìpínlẹ̀ Èkó** jẹ́ ìpínlẹ̀ kan ní gúúsù ìwọ̀-oòrùn Nàìjíríà láàárin àwọn ìpínlẹ̀ mẹ́rìndínlógójì náà, ó pọ̀ níye ó sì kéré ní ààyè. Ó sopọ̀ mọ́ gúúsù nípasẹ̀ àwọn ìgbèríko Benin àti sí ìwọ̀-oòrùn nípasẹ̀ ààlà òkèèrè pẹ̀lu Ìlu Benin, Ìpínlẹ̀ Èkó ń pín àwọn ààlà pẹ̀lú Ìpínlẹ̀ Ogun sí ìlà-oòrùn àti àríwá ní èyí tí ó mu jẹ́ ìpńilẹ̀ kan ṣoṣo ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tí ó pín ààlà pẹ̀lú ìpínlẹ̀ kan péré. Orúkọ fún ìlú Èkó — Ìlú tí ó pọ̀ jùlọ ní ilẹ̀ adúláwọ̀ — wọ́n dá ìpínlẹ̀ náà látara agbègbè Ìwọ̀ Oòrùn tí ó sì jẹ́ olú-ìlú tẹ̀lẹ̀rí ní ọjọ́ kẹtadínlọ́gbọ̀n oṣù karùn-ún, ọdún 1967.[4][5]

Gẹ́gẹ́ bí ìtọ́ka agbègbè, Ìpínlẹ̀ Èkó jẹ́ ilẹ̀ omi tí ìdá-mẹ́rin rẹ̀ dín ní díẹ̀ kúnfún òṣà, itọ́ àti àwọn odò.[6] Èyí tí ó fẹ̀ jù nínú àwọn omi wọ̀nyí ni ọ̀sà Èkó àti Lekki nínú ìpínlẹ̀ náà pẹ̀lú odò Ogun àti Osun tí ó ń sàn wọnú wọn. Àwọn omi yòó kù jẹ́ itọ́ tí ó ń sàn kiri ìpínlẹ̀ náà tí wọ́n sì jẹ́ ọ̀nà ìrìnàjò pàtàkì fún àwọn èèyàn àti àwọn ọjà. Nítòsí etí omi, ìpínlẹ̀ yìí bákan náà ṣàkónú àwọn onírúnrú ohun ọ̀gbìn, ẹranko àti ẹranmi gẹ́gẹ́ bí ẹjá ṣe wà náà ni àwọn ẹranmi ilẹ̀ adúláwọ̀ àti àwọn ọ̀ọ̀nì.[7][8]

Ìpínlẹ̀ Èkó ti jẹ́ ibùgbé fún ọdún tó ti pẹ́ nípasẹ̀ àwon ọ̀wọ́ onírúnrú ẹ̀yà onílùú, nípàtàkì awọn ọmọ Yoruba ni wọ́n ń gbé káàkiri ìpínlẹ̀ náà àmọ́ àwọn èèyan Ewe àti Ogu náà ń gbé ibi tí o nasẹ̀ lápá ìwọ̀ oòrùn.


Gẹ́gẹ́ bí àbáyọrí sísí lọ láti orílẹ̀ èdè kan sí òmíràn láti bíi ọ̀rúndún sẹ́yìn, ìpínlẹ̀ Èkó pẹ̀lú ti ní èrò tó pọ̀ tí wọn kìí ṣe àwọn ọ̀wọ́ ẹ̀yà orílẹ̀-èdè Nàìjíríà pẹ̀lú Edo, Fulani, Hausa, Igbo, Ijaw, Ibibio, àti èèyàn Nupe láàárin àwọn ọ̀wọ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà yòókù. Àwọn ọ̀wọ́ mìíràn wa látìta tí wọn wá láti àwọn ìlú tí ó pín ààlà orílẹ̀-èdè Nàìjíríà pẹ̀lú Saro (Sierra Leonean) àti Amaro (Brazilian) gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀wọ́ tí wọn ṣẹ̀ wá tí wọ́n kó lẹ̀ru tẹ̀lẹ̀rí tí wọ́n padà sílẹ̀ adúláwọ̀ ní àwọn ọdún 1800 pẹ̀lú àwọn àwùjọ ààrín ìlà-oòrùn orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tí wọ́n ti wà ti pẹ́ (pàápàá Syrian àti Lebanese orílẹ̀-èdè Nàìjíríà)[9] pẹ̀lú di èrò ní apákan gbòógì ní ìpínlẹ̀ Èkó pẹ̀lú àwọn tí wọ́n ṣí wá láìpẹ́ láti ìlu Benin, China, Ghana, India, Togo, àti United Kingdom.[10][11][12][13]

Babájídé Sanwóolú ni gómìnà ìpínlè Èkó.

## Ìpínlẹ̀ Èkó

**Ìpínlẹ̀**





Flag



Location of Lagos State in Nigeria

| | |
|---|---|
| **Orílẹ̀-èdè** | Nàìjíríà |
| **Ọjọ́ ìdásílẹ̀** | May 27, 1967 |
| **Olùìlú** | Ikeja |
| **Government** | |
| • **Gómìnà**[1] | Babájídé Olúṣọlá Sanwó-Olú (APC) |
| • **Àwọn alàgbà** | Munirudeen Muse<br>Ọlámilékan Adéọlá<br>Olúrẹ̀mí Tinúbú |
| • **Àwọn aṣojú** | Àkójọ |
| **Area** | |
| • **Total** | 3,475.1 km$^2$ (1,341.7 sq mi) |
| **Population** (2006 Census)[2] | |

| | |
|---|---|
| • **Total** | 9,013,534 |
| • **Density** | 2,600/km$^2$ (6,700/sq mi) |
| **GIO (PPP)** | |
| • **Ọdún** | 2007 |
| • **Total** | $33.68 billion[3] |
| • **Per capita** | $3,649[3] |
| **Time zone** | UTC+01 (WAT) |
| **ISO 3166 code** | NG-LA |
| **Website** | lagosstate.gov.ng (http://www.lagosstate.gov.ng) |

# Àwọn Ìtọ́kasí


1. See List of Governors of Lagos State for a list of prior governors
2. *"Lagos State - Population". Archived from the original on 2008-02-25. Retrieved 2009-07-22.*
3. *"C-GIDD (Canback Global Income Distribution Database)". Canback Dangel. Retrieved 2008-08-20.*
4. *Onyeakagbu, Adaobi. "See how all the 36 Nigerian states got their names". Pulse.ng. Archived from the original on 11 August 2022. Retrieved 25 December 2021.*
5. *"This is how the 36 states were created". Pulse.ng. 24 October 2017. Retrieved 22 December 2021.*
6. *"Lagos | Nigeria Education". nigeria-education.org. Retrieved 2020-05-30.*
7. Amao, J. O.; Oluwatayo, I. B.; Osuntope, F. K. (24 Oct 2017). "Economics of Fish Demands in Lagos State, Nigeria" (https://www.tandfonline.com/doi/abs/10.1080/09709274.2006.11905853?journalCode=rhue20). *Journal of Human Ecology* **19** (1): 25–30. doi:10.1080/09709274.2006.11905853 (https://dx.doi.org/10.1080%2F09709274.2006.11905853). https://www.tandfonline.com/doi/abs/10.1080/09709274.2006.11905853?journalCode=rhue20. Retrieved 2 January 2022.
8. *Olufowobi, Sesan (10 September 2018). "Sea cow rescued in Lagos". The Punch. Retrieved 2 January 2022.*
9. *"Lagos Population 2022 (Demographics, Maps, Graphs)". worldpopulationreview.com. Retrieved 2022-07-23.*
10. *Adeshokan, Oluwatosin (10 January 2020). "The last French speakers in Lagos". Mail & Guardian. Retrieved 3 January 2022.*
11. *"In Nigeria, Chinatown Vendors Struggle For Profits". NPR. Retrieved 3 January 2022.*
12. Fawehinmi, Yolanthe (26 October 2021). "Meet the British-Nigerians swapping London for 'Africa's Silicon Valley'" (https://www.telegraph.co.uk/family/life/meet-british-nigerians-swapping-london-africas-silicon-valley/). https://www.telegraph.co.uk/family/life/meet-british-nigerians-swapping-london-africas-silicon-valley/.

13. *Ndukwe, Ijeoma. " 'Everyone is hustling here': The Lebanese of Nigeria". Al Jazeera. Retrieved 2 January 2022.*

---

Jẹ́ kíkójáde láti "https://yo.wikipedia.org/w/index.php?title=Ìpínlẹ̀_Èkó&oldid=594542"